# Okunrin Kan To Jale N'ile Akintola Fewon Jura

IBADAN:— Ni opin ose to koja lo yi ni Adajo kotu kekerere ti ilu Ibadan pase pe ki omo odun mejidinlogun yara lo fi ewon osu mejidinlogun lori esun pe omo kunrin na ji ponun kan sile mesan ati kobo meta lowo okan ninu awon enia to lo si ile ibiti Oloye S L Akintola eniti ise Are O akakaufo ngbe titi di oj ku re ni Iyaganku nigbati awon en'a nse ibewo si ibiti nwon ti ya Ologbe na ni ojo kedogun osu kini odun yi

Ninu oro Olopa to ba odaran na se ejo ni o ti se alaye pe odaran na Titilayo Asani ji ponunkan sile mesan ati kobo meta (£1 9 3d) lowo Ogbeni David Selesi ni ogba to Ala—koso I,oba Ininle Iwo Orun Naijiria tele Oloye Samuel Ladoke Akintola ngbe tele ni ni ojo Abameta ti ise ojo kedogun osu

Nigbati adajo kotu na be re lowo odaran omokunrin na pe nje o ni oro kankan lati so ? odaran na si da adajo kotu na lohun pe o gba pe on jebi esun ti nwon fi kan an

Ninu idajo adajo kotu na ni o ti se alaye pe ko si sise ko si a'se ni o bi pase pe ki nwon mu okunrin na lo si ogba ewon ati pe ki o si fi ewon osu mejidinlogun lo jura.

## YE IRAWO RE WO

AQUARIUS (Jan 22 Feb 20) Mase nawo ni ina kuna ki o ba le dara fun o lojo iwaju nigbati owo miran ba tun de,

PISCES (Feb 21 Mar 20) Alafia yio de si o, ara re yio si le gingiri, to be ti iwo yio nitelorun lona gbo gbo, larin ile, ore ati ebi bi o ba si ri ona titun ti enia le fi ba won lo mase jafara.

ARIES (Mar 21 April 20) Mase da ise re ru ma si se jeki o pa o laiya o san ki o kuku din ise ti o nse lojo ku ki are ma ba mu o ki gbogbo ise re ma ba dau

TAURUS (April 21 May 20) Are fe mu o sugbon a ye ki o le gba ara re sile. o ye ki o lo fi ara re lele

GEMINI (May 21 June 21) Ojo oni dara ero okan re si dara pelu sugbon inawo airotele yio de si o, akoke asale yio si minringindin fun o iwo yio si gbadun awon alejo ti o wa ki o

CANER (June 22 July 22) Ise ti o fe se loni yio mo re ni yio si pekun re fun o da awon ise ti o ku duro ki o si lo fi ara lele

LEO (July 23—Aug 22) Iwo ko ni oyaya s'enia nitori ki o fi ara mo ohunkohun ti o ba de, sugbon ki o ma se omole

VIRGO (Aug 23—Sept 23) Igbehin ohun ti o da sile yio dara, iwo yio si tun ri nkan iyanu lati odo awon ore ati ebi wa

LIBRA (Sept 24—Oct 23) Gba ara re kuro lowo amodi ti o nfe se o. sina ire mbe fun o loni

SCORPIO (Oct 24—Nov 22) Baya o le se akiyesi wipe oro ara re ko [illegible] o ti ni lati lo ki o se suru ki [illegible], ko ni pe ka kuro.

SAGITTARIUS (Nov 23—Dec 21) Ki o dupe lowo ero re ti o pe iwo yio ri ire, asiri re si bo gbogbo ohun ti iwo ko ti ri aye lati yanju ni ki o mojuto

CAPRICORN (Dec 22—Jan 21) Oro awon ebi re i telorun, sugbon sibe are si mbe lara re, o ye ki o [illegible] ara lele, ki o si din ise re oni ku ki o ba r[illegible] aye mi.


# KERE O

Nje o ti ni ninu "IWE ITAN ODUDUWA tose sejade ?

Ha ! Kosemani ni iwe na je fun omo Yoruba Iwe na kun fun itan isedale Yoruba, Kedere ni aworan Oduduwa ati ti omo re han ninu re.

Mase jeki nwon rohin itan ilu re fun o

3/- pere ni. Postage 9d

Tete f'owo tire ranse si:-

ESAN KOGBOGUN SERVICE

8 Idumagbo Avenue Lagos Nigeria

## IWE KOSEMANI NI EYI

IWE ITOSE OHUN GBOGBO NINU ODU MERINDINLOGUN

Iwe yi kun fun Asotele ati wipe, yio din o lowo YEMIWO" ku, nitoripe iwo na yio le ma da se AYEWO fun ara re

KOSEMANI" ni iwe na, 2/6d pere ni a nta:- Postage 9d

ESAN KOGBOGUN SERVICE

8, Idumagbo Avenue
Lagos Nigeria (Leti Oja Jankara)

a successful future means planning *Now!*

Have you planned for the security of your family's future? Start a programme of Life Insurance NOW.

*with*

**GREAT NIGERIA INSURANCE Co. Ltd.,**

(INCORPORATED IN NIGERIA)

Enquire now for full details of our low cost endowment policy.

HEAD OFFICE:

39/41 MARTINS STREET,
P.O. Box 2314, LAGOS
TELEPHONE 25251.

BRANCHES AND AGENTS THROUGHOUT NIGERIA.

# Aladini Ti Se Ọmọ Ibrahim

## Lati Oju Ewe Keji

ile. ogbe ru Iya rẹ oni ko ma lo, nigbati ode (palace) afin oba ojoko o ko lesoro, ile kun. osc be to ola tunsọ las'n ọj maria. Nigba na o oba wa fura wipe obinrin tonwa njoko y ki obere lọwọ rẹ kini w se

Nigbati oba pe, ta ni ki lọ wase? Osi dahun o ni ẹ jẹki awali palu igbakeji ọba nigbati wọn bọ inu yara kan, Iya yẹn wasi esọ ti o fi bo gbogbo akan ti omu wa,

Nigbati o si, gbogbo inu ile wa mọlẹ dada. Ọba bere pe tani o ni ki on gbe eyi fun on? Iya yẹn dahun ni ọmọ on Aladini ni, oni on fi kini pi ta o lere, oni fẹfẹ Badru bado ọmọ rẹ.

O ba dahun wipe ki wọn si ooiri owo ki wọn fi gbe wa. Gbogbo inu ile si ko yẹri owa dabi mọnamọna gbogbo inu ile wa mọlẹ, Ọba ni wọn de pada oni ki Iya yẹn ma lọ oni un a pada fun ni esi obinrin yẹn jade.

O pada wa si ile, ojiṣẹ fun ọmọ rẹ Aldini wipe oba ni on ylo pada wa fun lesi.

nigbati iya yẹn lo tan Ọba pẹlu igbakeji rẹ ojomitoro lori ohunti Aladini wa fun ọba

Ọba bere lọwọ igbakeji rẹ wipe niẹ ori iru ori kini yi r? Igbakeji ọba kuna lati dahun o tun bi lerelekun si pe oje ori iru si r? Odahun wipe a ko ile ẹ bova ọmọ pa lero on tọju eyi lọ

Larin ojo mẹta si ara won da ọran larin ara wọn gbogbo ohunti Aladini ko wa fun ọba Nigbati o di alẹ wọn gbe Badri bado lo fun ọmọ igbakeji ọba la ti fi se aya

Nwọn wa tan mọLamọ ni si gbogbo arin ilu Iya Aladini o lọ si ọja ori gbo—gbo on ti wọn sesi ọja

O pada wa sọ fun ọmọ rẹ ohun on ti ariiya rẹ da—hun oni, nga ti sọ fun o nigbati o ni ki nkọ nkan latan ọba wipe ofẹrẹ ọmọ rẹ wo ti fi fun ẹlomiran Aladini sọ pe ki iya ou o fi wọn silẹ

Yọku Dola

# Ẹ maa Ka Iwe Irohin Imọlẹ





## Ila Kini Meyi




OGUN A PA YANMU—YANMU
OLORI ERIN MẸTA

Thre: Elephant Brand mosquito coils dara pupọ A ni O dara jui gbogbo ogun a pa yanmuyanmu yoku lọ.

O npa yanmuyanmn ninu ile ni kiakia orun rẹ si dara pupọ ju gbogbo ogun yanmuyanmu yoku lọ. Bakanna ni o si tun yara pa ayan ati idu ,

Tete lọ ra packet ogun yanmuyanmu, Three Elephant Brand coils tirẹ loni, ki o si danwo; iwọ y o ri bi o tiṣe pa gbogbo yanmuyanmu inu ile rẹ ti Iwọ ati awọn ọmọ rẹ 'yio si sun daradara

Ki o ri daju pe ogun yanmuyanmu ori erin mẹta ni nwọn mu fun ọ

Three Elephant mosquito Brand coils yi wa ni ṣọbu ls itaja kakiri Oriiẹ ede yi

Distributor

AMOS GBENLE & BROTHERS
34: Docemo Street Lagos.
6 & 11 Balogun Street West

BERE FUN OJULOWO EGBOGI—

## "Congreve's Iodo Form—Oinment



Atamatase ni egbogi " ADI-ELEGBO" yi i fun nọju gbo gbo orisirisi "EGBO—ESẸ" ni kiakia bi o ti wu ki jọ rẹ ti le pẹ to, Adielegbo yi ko ni ẹgbẹ nipa wipe awa ko ido i ni bi ẹr gbogbo ti ba wa loja egbo patapata jade o u e yio si mo daradara .Lẹhinna oju egbo yi o ba ji si u yio jẹ i oju re hu wa soke, yio si pọn daradara tun bakanna ko si mọ werewere ni ylo si san patapata Alafia de si ọ nlyen t —

Ri daju gbangba wipe awon sobu ti a da oruko won abssale iwe yi ni ogbe ranṣe lọ ra. Bibeko awon Elerọ ihii on ijibiti ylo ta 'Adamodi' re fun o maṣe gba rarao

Waterloo Medicine Stores
8 PalmChurch Street Lagos
22878 Lagos Nigeria (Ọja Ita Faaji)
UNITED DRUG CHEMIST
Alli Street Lagos

# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE TENI GBOGBO LAWA

NO 1,699 WEDNESDAY, FEBRUARY 16 1966 (2D)


## Ogogoro Baba !

IBADAN – Oju gba gbogbo awon enia ti nwon wa ni ile ejo kan ti ilu Ibadan ni ibere ose yi nigbati awon olopa mu odaran kan, Asani Taiwo eni odun mejilelogbon wa si ile ejo fun esun pe awon ba igo oti Ogogoro kan lowo re ni adugbo kan ti nwon npe ni Labintan.

Olopa to ba odaran na sejo se alaye fun ile ejo pe, nibiti awon gbe nse ise awon kakiri ni ojo na ni awon ba ri odaran na ti o gbe igo oti kan lowo ni ojo kedogbon osu kewa odun to koja.

Nigbati odaran na ri awon olopa, ko tile beru lati gbe oti ogogoro na pamo rara, nse lo tun gbe igo re soke ki awon tun le ba ri i daradara si ni owo re.

Nigbati odaran na rojo, ti o si gba wipe, on jebi esun na, ni adajo ba se idajo wipe, ki o lo fi ponun medogbon (£25) tanran si kotu, tabi ki o lo si ewon osu meji lafarabara.

### Olola Fajuyi So Pe :

# IJOBA OLOGUN YIO BA AWON OMO EGBE OSELU KAN S'EJO !

Lati Oju Ewe Kini

wa ni ipade na ni won bu si erin nigbati Olola Adekunle Fajuyi so pe on ko tun ni so ju eleyi lo lori oro yi titi di igbati Ijoba Ologun yio fi pari eto ti nwon nse lowo ti nwon yio si kede fun gbogbo awon enia lori oro na

Ogagun Fajuyi tun so pelu pe nigbati Ijoba Ologun yio ba kuro lori aga akoso ijoba, nwon yio ri daju wipe, awon omo egbe Oselu ti awon enia nfe, ti nwon si mo dada nipa eto Ijoba ni ijoba Ologun gbe akoso Ijoba na le lowo ki yio si je awon omo egbe Oselu ti awon ko mo nkan kan sugbon ti nwon nwa agbara ati ipo kakiri.

Sugbon Gomina na tun so fun awon enia wipe, nwon se dada ki nwon to gbe Ijoba na le awon enia ti nwon mo nipa eto iseju lowo wipe, ki nwon maa se Ijoba na lo.



Olola Adekunle Fajuyi

Gomina Ologun Agbegbe Iwo Orun

Olola Fajuyi so wipe, okan ninu awon ohun ti Ijoba Ologun nja fun nisisiyi ni wipe ki enikan mase tun ya enia kan soto mo ni Naijiria, wipe Yoruba Ibo tabi Hausa, sugbon ki gbogbo enia mo arawon ni omo ile Naijiria, ko si iyato kankan larin gbogbo wa ni Orile-ede t a gbe bi w si.

Ijoba yio fi opin si iwa iya enikan soto, ti nwon ko si tun ni gburo re mo laipe nile Naijiria.

### Irohin Otito

Irohin Eleyi ni Olola Fajuyi wa kilo fun awon Oniwe Irohin wipe ki nwon ma se pelepele ninu irohin ti nwon nte jade bi nwon ko ba fe ki Ijoba lo ase ti o wa lowo won lori Iwe Irohin, o ni ona ti awon enia miran ngba se Irohin je eyiti ko mu ogbon lowo.

Oniwe Irohin wa kan ran wa leti pe, ni Ojo Eti ti ise Ojo kerin osu yi ni awon Olopa mu Oloye Remi Fani Kayode pelu awon Minista meje miran pelu re.

Awon enia mejeje ti awon Soja ti mu na nisisiyi ni: Oloye Remi Fani Kayode eniti o ti fi igbakan je Igbakeji Alakoso Ijoba Ipinle Iwo Orun Naijiria ati Minista Alamojuto eto awon Ogbin.

Oba C. D. Akran, eniti o ti fi igbakan je Minista Alamojuto eto inawo tele ri Ogbeni Babatunji Olowofoyeku eniti o ti fi igbakan je Minista Alamojuto eto Idajo ati Ofin teleri, Ogbeni Okunola Adebayo, eniti o ti fi igbakan je Minista Alamojuto eto Abele fun Ijoba Ipinle Iwo Orun tele ri.

Ogbeni Salawu Fajinmi eniti o ti fi igbakan je Minista Alamojuto eto gbokegbodo, Ogbeni Nathaniel, Kotoye eniti o ti fi igbakan je Minista Alamojuto eto ise Owo ati ise Aje Ogbeni Adebiyi Adeyi eniti o ti fi igbakan je Minista Alamojuto eto ise Owo fun Ijoba Ipinle Iwo Orun.

Bakanna ni awon Soja ti tun mu awon enia merin miran pelu won oruko awon enia merein ti awon Soja ti tun mu pelu awon enia na ni wonyi:-

Ogbeni Richard Akinjide eni to ti figbakan je Minista Alamojuto eto eko fun apapo Ijoba Naijiria Alhaji Busari Obisesan eni to ti figbakan je Alaga ile Igbimo Ijoba Ipinle Iwo Orun ri Ogbeni Emmanuel Olakanmi eniti o ti figbakan je alaga ile ise eto ile ki ko ri ni Iwo Orun ati oloye Lalekan Salami eni to ti je Alaga ile ise Amuludagba fun Ijoba Ipinle Iwo Orun nigbakan ri

Gegebi Irohin ti a gbo okan ninu awon Oniwe Irohin wa kan fi ye wa wipe ni ojo Eti ti ise ojo kerin osu yi ni awon Soja lo mu awon enia na ninu ile won.

Siwaju eyi ni ati ngbo Irohin labele wipe, ohun ti o sele ri awon Olori egbe Demo, paapa julo Oloye Samuel Ladoke Akintola eniti o ti fi igbakan je Alakoso Ijoba Ipinle Iwo Osun tele ri ko dun mo awon omo egbe Demo ninu nwon si uwa ona lati le doju ti Ijoba Ologun eyiti Ogagun Aguiyi Ironsi je Olori re lowo bayi sbele ki nwon si pa Ijoba na re, ki awon Ologun na ma ba le se ise won mo.

Sugbon bi awo ti nlo, beeni awon tun njo bi nwon ti nyo wi beeni nyo gbo gbogbo eto ti awon enia na nse labele ni awon Soja ti gbo.

Siwaju eleyi ni awon Soja ti koko mu awon omo egbe Demo merin kan nitoripe nigba ti awon Soja lo tu ile won. Nwon bi we owo kan nibe ninu eyi ti awon ko oruko awon Olopa kan si ti nwon so wipe awon yio fan ni eegba marun ponun (£10,000)


Printed and Published by Mojuba Press Printers, ... Street, Lagos Phone 21985
Editor TUNJI ADE ... 25 Branco Street Lagos 16/2/66

28 FEB 1966


# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ORE AIYE TENI GBOGBO LAWA

NO 1,699 WEDNESDAY FEBRUARY 16, 1966 (2D)


## Ọlọpa Lọ Tu Ile Ọlọpa

ỌWỌ:- Ni ana ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kẹdogun oṣu yi ni awọn ọlọpa-nu kuro ni Ibadan ti nwọn si *lọ si* Ọwọ lati lọ tu inu ile ọkan ninu awọn ọga agba awọn ọlọpa Ọgbẹni Kofo Laṣekan, ti nwọn si tu gbogbo inu ile na lati oke delẹ.

Oniwe irohin v ni Ọwọ fi ye wa pe, jinnjinni dabo g awọn enia ti nwọn wa ninu ile na u awọn ọlọpa nu na wọle ti nwọn si bẹrẹ. tu inu ile na.

Nigbati awọn ọlọpa - nu na wọle tan, nwọn yi gbogbo ile na kakiri, nwọn ko si gba awọn enia inu ile na laye lati jade si ode titi ti nwọn fi tu inu ile na tan.

Lẹhinti nwọn tu ile na tan, ni nwọn wa mu awọn enia kan ninu awọn ẹbi ọga ọlọpa na, ti nwọn si mu wọn lọ si Ibadan lati lọ wadi ọrọ miran lẹnu wọn

Titi ti a fi nkọwe yi ni alẹ ana, a ko mọ ohunti awọn ọlọpa-nu nwa ninu ile ọga ọlọpa na, bi a ba si ti gbọ ọrọ na si ọo tun maa gọọ ninu iwe irohin wa.

# AWO YIO JADE !



Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ

OLORI ẸGBẸ AFẸNIFẸRE

IBADAN;— Gbogbo awọn enia ti nwọn wa ninu ipade ti Ọlọla Oga'gun Francis *A*dekunle Fajuyi Gomina Ologun Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ṣe ni ana ni nwọn ya ẹnu silẹ ti nwọn ko si le pade mọ, nigbati Gomina na nsọ ninu ipade awọn Oniwe Irohin wipe, Ijọba Ologun Naijiria ti ṣetan nisisiyi lati ba gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ Oṣelu kan ti awọn Ọlọpa ti mu ti nwọn si wa ni itimọle awọn Ọlọpa ṣe ẹjọ laipẹ-yi.

Ọrọ yi ni Ọlọla Adekunle Fajuyi nba awọn Oniwe Irohin sọ ni ana ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kẹdogun oṣu yi ninu ile iṣẹ rẹ ni Ibadan.

Ọlọla *A*dekunle Fajuyi tun ṣọ siwaju ninu ọrọ rẹ fun awọn Oniwe Irohin ti nwọn wa nibi ipade na wipe, Ijọba Ologun Orilẹ-ede ilẹ Naijiria yio sọ fun gbogbo aiye gbọ pe iru ẹṣẹ nla ti awọn ọmọ ẹgbẹ Oṣelu kan ti ṣe lẹnu igbati Ijọba Ologun ti bẹrẹ yi.

O tun sọ pẹlu wipe, nigbati Ijọba Ologun ba sọ iru ẹṣẹ nla ti awọn enia na ti ṣẹ, gbogbo enia ni ẹnu yio ya si ọrọ na, rara ni iru as k yi ti gbogbo enia nsọ wipe, ki Ijọba rere ati alafia le pada si Orilẹ ede yi.

Ki alafia ati ifaiyabalẹ le ba wa yika gbogbo awọn adugbo kan ti rogodo yan ti wa ri iati bi ẹnu jọ mẹta wa ti rukerudo ati rogodo yan si ti gbojikan yika gbogbo dugbo na,

### Ẹlẹwọn Oṣelu

Lẹhin d h si ọrọ yi ni Ọlọla Adekunle Fajuyi tun wa sọ fun awọn oniwe Irohin wipe, Ijọba Ologun yio da gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ Oṣelu ti nwọn wa ni ọgba ẹwọn nisisiyi silẹ laipẹ, ṣugbọn Ọlọla Fajuyi ko sọ as ko ti Ijọba Ologun na yio da gbogbo awọn enia ti awọn wa ninu ọgba ẹwọn silẹ.

Ṣugbọn gẹgẹbi alaye rẹ oni rohin wa ti lọ sibi ipade na ṣe alaye pe Ọlọla Adekunle Fajuyi sọ pe asiko na ko ni pẹ si asiko ti a wa ninu rẹ yi ti gbogbo awọn enia ti nwọn wẹwọn nitori ọrọ oṣelu yio fi jade ti Ijọba Ologun yio si ti awọn enia na silẹ

Gbogbo awọn enia ti nwọn Wo Oju Ewe K,fa

# Iwe si Olotu Irohin Imole

# Ijoba, E Fi Eyi S'ero

Mba sọpẹ gidigidi bi Olotu ba le gba mi laye ninu iwe Irohin rẹ akọmọlẹde eyiti o njade ni ojojumọ lati kesi Ijọba Orilẹ-ede Naijiria wipe ki nwọn jọwọ ki nwọn jẹki a ni ọkọ ofurufu kan ti yio maa pa ina.

Ohunti o mu mi da imọran yi ni wipe, ọpọlọpọ ilu larin ilu ati ni igberiko ni ina gbe ma njo bi o si jẹ wipe, awọn Panapana ki ni le gbe mọto wọn de ibiti ina na gbe njo.

Bi Ijọba ba le pese ọkọ ofurufu kan fun awọn Panapana lati ma a lo, nibikibi ti ina ba gbe njo, nwọn yio le ma a gbe ọkọ ofurufu na lọ atipe, eleyi yio si tun jẹki nwọn ma a tete de de ibẹ pẹlu.

Inu mi yio dun bi awọn alaṣẹ Ijọba ba le gba imọran yi yẹwo ki nwọn si pese ọkọ ofurufu na fun awọn Panapana, fun anfani gbogbo awa ara ilu.

Olotu, mo dupẹ fun aye ti ẹ gba mi, ọkọ Ọba ko ni ṣe nyin lẹṣẹ o.

Emi ni

Ọmọ Ọba 3. A. Mustapha
AGEGE.

## A Faramo Eto Akoso Ijoba Ironsi

Olotu, Dakun fun mi ni aye rampẹ ninu iwe nyin to njade lojojumọ ti o si nta bi akara gbigbona lati fi ye gbogbo awọn enia ilẹ Naijiria pe awa Olugbe ilẹ Ijẹbu fi ara mọ eto akoso Ijọba eyiti awọn Ṣọja ilẹ Naijiria ṣe Ikede rẹ pe awọn yio maa ṣe lati ọjọ kẹrin dinlogun oṣu ti o kọja lọ yi eyiti Ọgagun Aguiyi Ironsi yio jẹ Alakoso eto Ijọba awọn Ọmọ Ogun na

Eleyi jẹ ohun ti o dun mọ awa ọmọ ẹkun Ijẹbu to wa nile ati loko ninu lati le gbọ pe awọn Ṣọja lo gba eto akoso Ijọba eyiti awọn ẹgbẹ Oṣelu ti nṣe tẹlẹ ati pe lati igbati nwọn ti ṣe ikede na ni alafia ifọkanbalẹ ati eto Ijọba rere ti bẹrẹsi padabọ si Ipinlẹ Iwọ Orun ati papa julọ ni ẹkun Ijẹbu eyiti a ti wa ninu ewu lọwọ Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun.

Adura wa ni pe ki Ọlọrun jẹki asiko ti awọn Ṣọja gba Ijọba na dara fun wa ki ile roju ki a ni owo lọwọ ki ifọkanbalẹ si de ba gbogbo wa ni'le ati loko Amin.

Olotu, ẹ ku iṣẹ o ajiade yio ma jẹ o.

Emi ni
Olatunde Dauda
Odolowu IJẸBU ODE

## A Ngbadun Itan Soyinka

Olotu, Inu mi yio dun bi ẹ ba jẹki ọrọ mi kekere yi jade la ti dupẹ lọwọ Ọgbẹni J. O. Shoyinka opitan igbo ọrọ Abidodo ma je lori itan aladun to nsọ sinu iwe Irohin Imọlẹ ati pe inu mi yio dun bi ọgbẹni Shoyinka ba le tete jẹki a ri aworan rẹ ninu iwe na ati lati le mọ iru enia ti opitan na jẹ ati pe ki a le mọ ti a ba ri ni adugbo ilu Eko tabi pe ki a ba ṣe alabapade.

Itan ọgbẹni yi si dabi ẹni pe nṣe ni mo nri awọn enia to sọrọ rẹ na gẹgẹbi o tiṣe ri lọkan mi ati pe o tun dabi ẹnipe oju mi gan an ni iṣẹlẹ na ti ṣẹlẹ.

Inu wa yio dun bi opitan na ba le tun fun wa ni itan miran ti eleyi ba si pari ati wipe, ao si ma reti Aworan Ọgbẹni Shoyinka ninu iwe na laipẹ yi, Olotu mo dupẹ aye ti ẹ gba mi.

Emi ni

Kọla Ajayi

Mushin


GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN ATI OGO NIPA **DYNAMIREN** TỌNIKI



ALE-IBI-ALE Egbogi Tọ ki amọnu, titun ti gbogbo ara Ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ [illegible] Agbara ati Ajẹbidan ṣẹ lara agbalagba Ọkunrin ati Obinrin gbogbo

Bi arẹ ara ba nmu ọ, ni gbakugba fun wahala tabi iṣẹ ṣiṣe ti o ko le jẹun dara dara, tabi ki o male sun dada de ọkan lọsan tabi awọn ṣan ara rẹ gbogbo ki ṣe fun daradara ti Emi Breath inu ko ba kunlẹ daradara wọn iṣẹ tabi wahala sise tabi inu awọn ailera gbogbo nyin ti ọjọ ori (age) ba ti kọja ogbọn ọdun si adọrin tabi jubẹ lọ mọ daju pe DYNAMIREN ni egbogi ti o nfẹ lati sọ ara rẹ di ọtun pata pata oju rẹ yio si walẹ re kete alafia ati Igbadun de Bere Dynamiren yi ni Ṣọbu awọn :-

Waterloo Medecine Stores
8, Palm Church Street P. O Box 333 Lagos

LAGOS ISLAND CHEMIST
Nnamdi Azikiwe Street, Lagos
UNITED DRUG CHEMIST
Alli Street, Lagos.

ADEDUN CHEMIT
14, Wakeman Street

ATI NI ṢOBU
ṢE OLODUMARE DISPENSARY OKE BOLA IBADAN



# KERE O! KERE O!!

## Awọn Tani Wọnyi ?



LATI ỌWỌ OSI:- ỌNI ADELẸKAN (Olubuse) ẸNIKEJI:- ỌNI ADEMILUYI (Ajagun) ẸNIKẸTA:- ỌNI ADEREMI (Atọbatẹle)

AWỌN ỌMỌ ODUDU WA MẸTA TO JOYE 'ỌNI' TẸLE ARA WỌN

ITAN WỌN DUN KA

N ẹ o ti [illegible] Igbesi aiye Odudua ati ti awọn ọmọ rẹ" to ṣẹẹ de?

Bi o ko ba ti ra a mi ṣe jafara, nitoripe, bi awo ran awọn 'ỌNI' mẹta si ti ṣe jẹ ohun iyanu la ti le ri wọn papọ, bẹni itan wọn rẹ ninu iwe ka.

Maṣe ẹ ki awọn to [illegible] rẹ fun ọ, tete lo ra tire koto [illegible], 3/- pere ni, Post age 9d

Fowo tire ranṣẹ si.—
ẸSAN KOGBOGUN SERVICE
8 Idumagbo Avenue
Lagos Nigeria.
(Leti oja Jankara)